# Ááwọ̀ àti Ìpẹ̀tù-sáàwọ̀ nínú Ewì Adébáyọ̀ Fálétí

**Ìṣọ̀lá Sauban Àlàdé**
*Department of Linguistics and African Languages*
*Obafemi Awolowo, University, Ile-Ife*
*isholasauban@gmail.com*
*fathfaith53@gmail.com*

## Àṣamọ̀
*Ìwádìí yìí fi hàn pé inú ọkàn ènìyàn ni 'ọ̀rọ̀', 'afọ̀', 'èdè', 'ìhónú', 'ìdùnnú', 'ìbànújẹ́', àti orísìí àwọn ìṣesí àti ìhùwàsí mìíràn pabùdó sí. Ọkàn yìí ní ń gbé ọ̀rọ̀ (tútù) tíí yọbì lápò àti ọ̀rọ̀ (burúkú) tíí yọdà lápó jáde. Onírúurú onímọ̀ ni wọ́n ti ṣe ìwádìí lórí ohun tó ń ṣe okùnfà aáwọ̀ láàrin àwùjọ ènìyàn. Àrífàyọ ìwádìí yìí lórí iṣẹ́ àwọn onímọ̀ ìṣáájú bẹ́ẹ̀ fi hàn pé kókó-ọ̀rọ̀ ìjẹgàba àti ìwà ìfọlájiyọ̀ ni olúborí okùnfà aáwọ̀ ní ìbámu pẹ̀lú ìfojú-èrò-Karl-Marx-wo-ìṣẹ̀lẹ̀-inú-àwùjọ. Nínú ìwádìí yìí ni a ti fi hàn pé, ọpọ́n ìmọ̀ tó sún síwájú lórí ìgbòkègbodò àwọn ẹ̀dá ènìyàn àti ìbára-ẹni-gbépọ̀ wọn ni ó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, àwọn ìwà tó tayọ ìjẹgàba náà a tún máa ṣe okùnfà aáwọ̀. Èyí ló bí èrò àwọn agbátẹrù tíọ́rì aáwọ̀ àti ìpẹ̀tù-sí-i. Ní báyìí, àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ àti ìmọ̀ ajẹmọ́-iṣẹ́-ọkàn náà dá sí ọ̀rọ̀ nípa orísun aáwọ̀ yìí láàrin àwùjọ ènìyàn. Iṣẹ́ ìwádìí yìí wá gùn lé ìlànà ti àwọn onímọ̀ ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn láti tọpinpin àwọn èdè ajẹmọ́-aáwọ̀ àti èdè àmúlò fún ìpẹ̀tù-sáàwọ̀ láwùjọ ènìyàn nínú àṣàyàn àwọn ewì Adébáyọ̀ Fálétí. Àwọn èdè ajẹmáàwọ̀ mẹ́wàá àti èdè àmúlò fún ìpẹ̀tù-sáàwọ̀ mẹ́wàá ni a fi ṣe òdiwọ̀n ìwádìí wa. Ìwádìí yìí tọ́ka sí ìlànà tí Adébáyọ̀*

*Fálétí ń gbà kìlọ̀ fún wa láti dẹ́kun lílo àwọn èdè tí ó jẹ mọ́ aáwọ̀ nínú àwùjọ wa nínú àwọn ewì rẹ̀. Lóòótọ́ ni pé, kò lè ṣe kí ìjà má wà. Nítorí pé, arẹ́májà kò sí ajàmáparí ni kò sunwọ̀n. Síbẹ̀ náà, a níláti dẹ́kun àwọn èdè tó ń dá aáwọ̀ sílẹ̀ nínú àwùjọ. Ìdí ni pé, ọ̀rọ̀ (tútù) a máa yọ obì nínú àpò, tí ọ̀rọ̀ (burúkú) a sì máa yọ idà nínú apó. Èébú, èpè, àpará akọ, ẹ̀fẹ̀, òwe (abàmì), èdè ẹ̀gàn, èdè àbùkù, èdè ìgbéraga àti àwọn èdè tí ó jẹ mọ́ irọ́ pípa ni orírun aáwọ̀ láàrin àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ìwádìí yìí ti fi hàn. Àbájáde ìwádìí yìí ni pé, ipò tí ọkàn ènìyàn bá wà ní àwọn àyè kan lè ṣe okùnfà aáwọ̀, ó sì tún lè pẹ̀tù sí aáwọ̀ lọ́nà mìíràn. Nítorí ìdí èyí, a níláti máa ṣe àkíyèsí èdè tí a ó máa lò lásìkò ìbínú, kí á lè dẹ́kun lílo èdè tí ó ń ṣe okùnfà aáwọ̀ láàrin àwùjọ.*

**Kókó ọ̀rọ̀:** Ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn, Adébáyọ̀ Fálétí, aáwọ̀, ìpẹ̀tù-sááwọ̀, , ìkóra-ẹni-níjàánu.

## Ìfáárà

Aáwọ̀ ni àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ abáyému tí ó kún fún aburú àti ìrúkèrúdò nínú ìhun àwùjọ. Kò sí àwùjọ tí aáwọ̀ kò ti lè wáyé. Aáwọ̀ lè jẹ́ ìṣẹ̀lẹ̀ tó wáyé látàrí àìgbọ́ra-ẹni-yé tàbí ìwà ìjẹgàba tí àwọn kan hù síra wọn. Ohun tí ẹnìkan ṣe, tí ẹlòmíràn kò ní ìfẹ́ sí ni aáwọ̀. Fún ìdí èyí, kí aáwọ̀ tó lè wáyé, àjọṣepọ̀ gbọ́dọ̀ wáye láàrin àwọn ẹ̀dá. Níwọ̀n ìgbà tí a bá ti rí ẹ̀dá abẹ̀mí nínú àwùjọ kan tí àjọṣepọ̀ ń wáyé láàrin wọn, dandan ni kí àìgbọ́rayé àti àwọn ohun tí a kò nífẹ̀ẹ́ sí máa wáyé láàrin wọn. Àwọn ẹ̀dá abẹ̀mí tí à ń sọ yìí lè jẹ́ ènìyàn, ẹranko, ẹyẹ, ẹran ilé, kòkòrò àti onírúurú àwọn ohun abẹ̀mí mìíràn tí Olódùmarè dá. Ìdí nìyí tí a fi gbọ́dọ̀ máa kíyèsára

láàrin àwa ẹ̀dá ènìyàn pé, ibikíbi tí aáwọ̀ bá ti ṣẹ́yọ, àdánwò ni, kí á sì tiraka láti wá ọ̀nà tí a ó fi borí àwọn àdánwò náà.

Ìdàkejì aáwọ̀ ni pẹ̀lẹ́kùtù. Kí ohun tí kò wọ̀ wáyé, kí á sì fi eegun òtòlò tò ó ni ilé-ayé fi lè rọgbọ fún ẹ̀dá ènìyàn, nítorí pé arẹ́májà kan kò sí, ajàmáparí ni kò dára. Ìṣòro tí ó kárí-ayé ni aáwọ̀ láàrin àwọn aláwọ̀dúdú tàbí àwọn aláwọ̀funfun káàkiri àgbáyé. Èyí túmọ̀ sí wí pé, láti ìgbà tí Aláyé ti dá ayé, ni ọ̀rọ̀ nípa aáwọ̀ ti ń ṣẹlẹ̀ nínú àwùjọ ènìyàn. Tí a bá tilẹ̀ kíyèsí àwùjọ Yorùbá nínú àwọn ìtàn-ìwáṣẹ̀ wọn, a óò rí i pé ọ̀rọ̀ nípa aáwọ̀ kì í ṣe ohun ọ̀tun, àdáyébá ni. Síbẹ̀ náà, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé dandan ni kí aáwọ̀ parí ní ibikíbi tí aáwọ̀ bá ti ṣẹ́yọ bíi ṣẹ́lẹ̀rú. Àwọn Imọlẹ̀ tí wọ́n rọ̀ wá sáyé láti òde-ọ̀run pẹ̀lú àwọn Ẹlẹyẹ náà jà lójú ọ̀nà kí wọ́n tó padà rẹ́ (Abímbọ́lá, 1977:27).

Onírúurú aáwọ̀ ló wà láàrin ọkùnrin sí ọkùnrin tàbí láàrin obìnrin sí obìnrin. Aáwọ̀ tún lè wáyé láàrin ọkùnrin àti obìnrin tàbí láàrin ọmọdé àti àgbà. Ó lè jẹ́ aáwọ̀ lórí ilẹ̀ dídà, owú jíjẹ, ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn, okòwò, orogún ṣíṣe, ogún pínpín, èké ṣíṣe, olè jíjà àti oríṣìí àwọn nǹkan mìíràn bẹ́ẹ̀. Abímbọ́lá (1977:47) tilẹ̀ sọ pé:

> Èké níí pẹrú
> Èpè níí polè
> Ilẹ̀ dídà níí pọ̀rẹ́
> Alájọbí níí payèkan tó bá ṣebi
> Àṣẹ́ dọwọ́ ilẹ̀ a jọ mú.

Àyọlò òkè yìí ṣe àfihàn díẹ̀ lára àwọn ohun tó lè ṣe okùnfà aáwọ̀ gẹ́gẹ́ bí ojú-àmúwayé àwọn Yorùbá. Bí ènìyàn bá wá fẹ́ dẹ́kun aáwọ̀ tí èké ṣíṣe ń ṣe okùnfà rẹ̀, dandan ni kí

wọ́n jáwọ́ nínú èké ṣíṣe gan-an. Ìwà olè jíjà náà jẹ́ ọ̀kan lára ìwà tí kò wọ̀, tí kò bójúmu, tí kò sì bá àṣà àwùjọ Yorùbá rẹ́. Bí ọ̀rẹ́ bá ń dalẹ̀ ọ̀rẹ́ tàbí kí tọkọ taya máa dalẹ̀ ara wọn, aáwọ̀ ni. Ọ̀nà tí a sì lè gbà yanjú àwọn ìṣòro wọ̀nyí ni dídẹ́kun àwọn ìwà ìbàjẹ́ tó rọ̀ mọ́ wọn, kí àtúnbọ̀tán wọn tó wáyé.

Nínú ìpèdè àwọn Yorùbá, à ń rí àwọn ọ̀nà àbáyọ tí wọ́n ti là kalẹ̀ fún dídẹ́kun aáwọ̀. Ìdí ni pé, wọ́n gbàgbọ́ pé a lè lo ọ̀rọ̀ ẹnu tàbí lítírèṣọ̀ alohùn láti yanjú aáwọ̀. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ipò tí ọkàn ènìyàn bá wà lè fa ìhónú tàbí ìbínú fún un. Ọ̀rọ̀ tí ènìyàn bá sì gbọ́ ní àsìkò náà lè pẹ̀tù sí i lọ́kàn tàbí kí irúfẹ́ ọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ túbọ̀ dá kún ìbínú rẹ̀. Ẹ̀yí ló mú kí àwọn Yorùbá máa sọ pé, bí etí kò gbọ́ yìnkìn, inú kì í bàjẹ́. Ọ̀kan lára àwọn akéwì tó sì mọ tìfun tẹ̀dọ̀ ọ̀rọ̀ àti èdè ìjìnlẹ̀ tí a lè lò láti yánjú àwọn ìṣòro inú àwùjọ ni Adébáyọ̀ Fálétí jẹ́. Bí ó ti ń fi èdè ìjìnlẹ̀ Yorùbá dá aṣọ ró ìwé ìtàn-àròsọ rẹ̀ àti eré-onítàn, ló tún ń fi ìjìnlẹ̀ èdè ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ewì tí ó kọ. Ọlátúnbọ̀sún Ọládàpọ̀ nínú Ọlátúnjí (1982: iii) tilẹ̀ júwe Ọ̀jinmì Akéwì yìí pé:

> Igúnnugún ni wọ́n ń rí tí wọ́n ń dáṣàa gbàguruyẹ.
> Àkàlàmàgbò làwọ́n rí tí wọ́n ń dáṣàa bàgẹ̀bàgẹ̀.
> Adébáyọ̀ Fálétí ni wọ́n ń rí tí gbogbo ayé ń dáṣà ewì kíké.
> Ọmọ Fálétí dágbo ijó, ẹ forin fún ẹni tó lorin
> Àgbà nínú akéwì tí í sọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀.
>
> (Ọlátúnbọ̀sún Ọládàpọ̀).

Òjìnmì akéwì ni Adébáyọ̀ Fálétí. Onírúurú ọ̀nà ló sì ń gbà lo àwọn ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ rẹ̀. Lára àwọn ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí a mọ̀ mọ́ Adébáyọ̀ Fálétí ni àwọn ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó fi máa ń yanjú aáwọ̀ láàrin àwùjọ. Nínú ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ Adébáyọ̀ Fálétí tí ó sọ di ewì nínú ìwé ìtàn-àròsọ, eré-onítàn pẹ̀lú ìwé ewì rẹ̀ ni a sì ti ṣe àṣàyàn àwọn èdè tí ó jẹ mọ́ aáwọ̀ àti ìpẹ̀tùsááwọ̀ tó kàn wá nínú iṣẹ́ yìí.

## Ìtumọ̀ tí a lè fún Aáwọ̀

Ohun tí kò wọ̀ ni Yorùbá ń pè ní aáwọ̀. Ó ní í ṣe pẹ̀lú ìṣẹ̀lẹ̀ tí a kò nífẹ̀ẹ́ sí tàbí ìwà tí a kò fi ara mọ́. Ibi ìkùnsínú ni aáwọ̀ ti ń bẹ̀rẹ̀, tí yóó sì di ọ̀tẹ̀ àti ogun. Kì í ṣe gbogbo aáwọ̀ ní ń di ogun, ṣùgbọ́n, ọ̀tẹ̀ ló máa ń tẹ̀lé aáwọ̀. Aáwọ̀ lè jẹ́ odì yíyàn tí kò ní í fa ìjà tàbí ìtàpórógan. Ó lè padà di ogun bí odì yíyàn náà kò bá tán bọ̀rọ̀. Lára àwọn ohun tí ń ṣe okùnfà aáwọ̀ ni àwọn ọ̀rọ̀ abínúkú tí à ń pè ní ìpèdè òdì. Bí a bá sọ̀ọ̀rọ̀ kòbákùngbé sí ènìyàn, inú lè bí ẹni náà, tí ìwà rẹ̀ yóò sì yí padà. Yàtọ̀ sí ìpèdè òdì, aáwọ̀ a máa wáyé lórí ohun-èlò tàbí àwọn ohun pàtàkì tí a lẹ́tọ̀ọ́ sí, ṣùgbọ́n, tí ọwọ́ wa kò tẹ̀ ẹ́ látàrí ìwà ìjẹgàba tí àwọn alágbára tí nǹkan náà wà ní ìkápà wọn hù sí wa. Bí èyí bá wáyé, inú ènìyàn kì í dùn, yóò sì máa kó ìbànújẹ́ bá a ní gbogbo ìgbà. Aáwọ̀ tí à ń wí yìí lè wáyé láàrin ìlú sí ìlú, ìletò sí ìletò, orílẹ̀-èdè sí orílẹ̀-èdè, ọ̀rẹ́ sí ọ̀rẹ́, ọkọ sí aya, ọ̀gá sí ọmọṣẹ́, àti láàrin mọ̀lẹ́bí. Ìlara ṣíṣe náà a máa fa aáwọ̀. Díẹ̀ lára àwọn onímọ̀ tí wọ́n ti ṣiṣẹ́ lórí ìtumọ̀ àti àpèjúwe ohun tí aáwọ̀ jẹ́ ni Schwiriz (1965), Ajíbadé

(2009), Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2009), Adéyẹmọ (2011), Louis-Gate (2014), Tábí-Àgòrò (2017), Ibrahim (2018), àti Howell (2018). Schwiriz (1965:109) sọ pé:

> In literature, a conflict is an event, circumstances, person or personal characteristics that stands in the way of a character's pursuing goals.
>
> Nínú ìmọ̀lítíréṣọ̀, aáwọ̀ ni ìṣẹ̀lẹ̀, ìdíwọ́, ènìyàn tàbí àbùdá àdáni tí ó ń dúró bí ìdènà fún èròǹgbà ẹ̀dá-ìtàn lórí ìlepa rẹ̀.

Onímọ̀ yìí gan-an ló fún wa ní ìtumọ̀ tó bá àfojúsùn iṣẹ́ yìí mu lorí irúfẹ́ aáwọ̀ tí à ń ṣe ìwádìí lé lórí. Ìdí ni pé, aáwọ̀ tí ń ṣe ìdènà fún èrò-ọkàn tàbí èyí tí èròkerò inú ọkàn ènìyàn ṣe okùnfà rẹ̀ ni ó jẹ wa lógún jù lọ nínú ìwádìí yìí. Ohun tí ènìyàn rò lọ́kàn ló máa ń fọ̀ jáde lẹ́nu. Bí aáwọ̀ bá ṣẹlẹ̀ láàri ènìyàn méjì tàbí ọ̀pọ̀ ènìyàn, yóò gún wọn ní kẹ́ṣẹ́, tí ìwà àti ìṣesí wọn sì lè yí padà. Ìpèdè òdì sì lè ṣẹlẹ̀ láàri àwọn tí aáwọ̀ bẹ́ sílẹ̀ láàrin wọn. Bí ènìyàn bá kó ara rẹ̀ ní ìjánu ní irú àkókò tí àwọn aáwọ̀ yìí ń ṣẹlẹ̀, aáwọ̀ náà lè dínkù tàbí kí ó yanjú. Ìtàpórógan, ìjà, ìkùnsínú, àti oríṣìí àwọn ìkọlura tó ń wáyé láàrin àwọn orogún ni Ajíbádé (2009: 110-121) tọ́ka sí nínú iṣẹ́ rẹ̀. Onímọ̀ yìí fi yé wa pé, irúfẹ́ aáwọ̀ àárin àwọn orogún yìí a máa dogun dọ̀tẹ̀, ó sì lè tú agboolé ká.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2009) náà tọ́ka sí onírúurú aáwọ̀ tí ń wáyé láàrin takọ-tabo láwùjọ àti àwọn ohun tó máa ń ṣe okùnfà rẹ̀. Onímọ̀ yìí náà fi yé wa pé agbára àwọn obìnrin ju

ti àwọn ọkùnrin lọ ní gbogbo ọ̀nà. Fún ìdí èyí, aáwọ̀ a máa ṣẹ̀lẹ̀ láàrin àwọn ọkùnrin àti obìnrin lóòrèkóòrè tí àwọn ọkùnrin bá tasẹ̀ àgẹ̀rẹ̀. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2009: 164) tilẹ̀ sọ pé, ní èrò tirẹ̀, “women are more powerful than men in Yorùbáland.” Èyí túmọ̀ sí pé “Àwọn obìnrin lágbára ju àwọn ọkùnrin lọ ní ilẹ̀ Yorùbá” Agbára ẹ̀mí-àìrí àti agbára àbùdá-àdámọ́ àwọn obìrin ni Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2009: 164) ń sọ. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2009) wá fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, bí àwọn ọkùnrin bá ń fẹ́ dẹ́kun aáwọ̀ tàbí kí wọ́n fi òpin sí i láàrin àwùjọ wọn, wọ́n gbọ́dọ̀ fi ọ̀wọ̀ agbára ẹ̀mí-àìrí àti agbára àbùdá-àdámọ́ àwọn obìnrin wọ̀ wọ́n.

Ìwádìí Adéyẹmọ (2011) náà dá lórí ètò-ìṣèlú. Èyí ló mú kí onímọ̀ yìí tọ́ka sí abala ibi tí aáwọ̀ ń gbà wọ inú àwùjọ nípasẹ̀ àwọn òṣèlú. Adéyẹmọ (2011: 107) gbà pé, àìṣedéédé àwọn adarí ìlú lórí ojúṣe wọn fún àwọn ará ìlú ló ń ṣe okùnfà aáwọ̀ láàrin wọn. Onímọ̀ yìí tún fi yé wa pé, àwọn òṣèlú gan-an ni wọ́n ń ṣe okùnfà aáwọ̀ tí ńṣẹlẹ̀ láàrin àwọn ará ìlú sí ará ìlú. Bí a bá tẹ̀lé èrò onímọ̀ yìí, aáwọ̀ tí oun ń júwe tayọ irúfẹ́ aáwọ̀ tí ń ṣẹlẹ̀ nípasẹ̀ èdè-àìyedè, ìbínú, àìgbọ́rayé, àti ìlara ṣíṣe. Aáwọ̀ tí onímọ̀ yìí júwe jẹ mọ́ ìjẹgàba. Kì í ṣe ìjẹgàba nìkan ni ó ń fa aáwọ̀. Àwọn ìṣesí, ìhùwàsí àti ìrísí tí ènìyàn kórìíra a máa fa aáwọ̀ bí wọ́n bá hu àwọn ìwà náà sí wa. Louis-Gates (2014:118) tilẹ̀ sọ pé:

> Conflict is a serious disagreement and arguments about something important. If two people or groups are in a serious conflict, they have had a serious disagreement.

> Aáwọ̀ jẹ́ àìgbọ́rayé tàbí àríyànjiyàn tó wáyé lórí nǹkan tí ó ṣe pàtàkì sí wa. Bí aáwọ̀ bá wáyé láàrin àwọn ènìyàn méjì tàbí àgbájọpọ̀ àwọn ènìyàn, ó túmọ̀ sí pé àìgbọ́rayé tó burú ti wáyé láàrin wọn ni.

Lóòótọ́ ni àìgbọ́rayé lè ṣe okùnfà aáwọ̀ gẹ́gẹ́ bí Louis-Gates (2014:118) ti sọ, ṣùgbọ́n, àwọn ohun tí ènìyàn kò ní ìfẹ́ sí tí àwọn mìíràn sì ń ṣe é fún un tàbí tí wọ́n fi hùwà sí i gan-an ni ó burú jù lọ nínú irúfẹ́ aawọ̀ tí ń wáyé láàrin àwọn ènìyàn. Tábí-Àgòrò (2017:10) sọ pé:

> Bí aáwọ̀ tàbí àìgbọ́rayé bá wáyé láàrin orogún méjì, ọṣẹ́ ńlá ló máa ń ṣe fún ọkọ àti àwọn ọmọ wọn. Okùnfà aáwọ̀ yìí sì ni èmi-ò-jù-ọ́-ìwọ-ò-jù-mí tó máa ń wà lọ́kàn àwọn orogún náà sí ara wọn.

Bí a bá mú èrò-ọkàn ní ọ̀kúnkúndùn lórí ọ̀rọ̀ aáwọ̀ gẹ́gẹ́ bí Tábí-Àgòrò (2017:10) ti sọ, ó yẹ kí á mọ ọ̀nà àbáyọ sí ìṣoro tí aáwọ̀ ń dá sílẹ̀ láwùjọ wa. Ìdí ni pé, kìí ṣe gbogbo ìgbà ló yẹ kí aáwọ̀ máa ṣẹlẹ̀ lórí ohun tí kò tó nǹkan. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ọmọ àlè ní í rínú tí kì í bí, ọmọ àlè náà ni a sì ń bẹ̀ tí kì í gbọ́. Nítorí náà, ìkóra-ẹni-níjàánu lórí àwọn èròkerò tó ń ṣẹ́yọ sí wa lọ́kàn ní àsìkò tí aáwọ̀ bá ṣẹlẹ̀ ni ó ṣe pàtàkì jù lọ́. Èrò wa yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí Ibrahim (2018:215) fi yé wa pé:

> Ìṣòro ńlá ni èdè-àìyedè, ìkùnsínú, àìgbọ́rayé àti aáwọ̀ jẹ́ láwùjọ. Àwọn nǹkan wọ̀nyí kì í jẹ́ kí ètò-ìbagbépọ̀ àwùjọ ènìyàn lójútùú. Ohun tí ó ṣe pátàkì jù lọ ni ojú tí ènìyàn bá mú wo

> àwọn nǹkan wọ̀nyí. Bí a bá rí wọn bí ìṣòro tí kò lè yanjú, ogun àti ọ̀tẹ̀ ló máa ń dà, ṣùgbọ́n, bí a bá ronú pé dandan ni wọ́n jẹ́ nínú ètò-ìbágbépọ̀ àwùjọ ènìyàn, bíńtín ni ìṣòro wa yóò jẹ́ láwùjọ.

Ohun tí a ní lọ́kàn gan-an ni onímọ̀ yìí sọ yìí. Níbikíbi tí aáwọ̀ bá ti wáyé, a níláti kíyèsí ipò tí ọkàn wa wà, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, yóò nira láti kó ara wa ní ìjánu. Sùúrù àti ìwà pẹ̀lẹ́ ni a lè fi tán ìṣòro yìí. Bí bẹ́ẹ̀ kọ́, èdè òdì tó máa ń wáyé lásìkò tí ènìyàn ń bínú ni yóò máa jáde lẹ́nu wa. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ẹyin lohùn, bí ó bá bọ́ lulẹ̀, kò ní í ṣeé kó mọ́. Èdè àpárá lásán lè di aáwọ̀, ìjà, ọ̀tẹ̀ àti ogun, ṣùgbọ́n, bí a bá mú un bíńtín, ìgbọ́rayé yóó wà.

Aáwọ̀ ni ìṣẹ̀lẹ̀, ìṣesí, ìhùwàsí, ìgbékalẹ̀, èrò, ìpèdè, àti àwọn nǹkan mìíràn tí a kò ní ìfẹ́ sí nígbà tí ó wáyé. Ìhà tí a kọ sí aáwọ̀ ṣe pàtàkì. Bí èròkerò bá wá sí ènìyàn lọ́kàn nígbà tí aáwọ̀ wáyé, ó lè fa àìsàn, ikú, ogun, ọ̀tẹ̀, ìjà, àti oríṣìí àwọn ohun burúkú mìíràn. Bí a ba kó ara wa ní ìjánu lórí èrò-ọkàn wa nígbà tí aáwọ̀ wáyé, a lè ronú kan ọ̀nà àbáyọtí aáwọ̀ náà yóò fi parí.

## Tíọ́rì Àmúlò fún Iṣẹ́ yìí

Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn (Psycho-Social) ni a lò fún ìwádìí yìí. Tíọ́rì méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó papọ̀ di tíọ́rì yìí. A lo abala kan nínú àfojúsùn àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ (Sociology of literature), tí ó jẹ mọ́ èrò Hypolyte Taine (1963) àti ìmọ̀ ajẹmọ́-ìṣe-ọkàn (Psycho-analysis

theory) tí òun náà jẹ mọ́ èrò Piaget (1932). Àwọn tíọ́rì méjèèjì wọ̀nyí ni ó di ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn tí a lò fún ìwádìí yìí. A ó ṣe àyẹ̀wò àfojúsùn àwọn agbátẹrù tíọ́rì méjèèjì láti tọ́ka sí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí a sọ di ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn yìí nínú àfojúsùn wọn.

## Ìfojú-Ìmọ̀-Ìbágbépọ̀-wo Lítíréṣọ̀

Abala mẹ́rin ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí là kalẹ̀ fún olùwádìí tàbí ẹni tó ń ṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ láti kíyèsí nínú iṣẹ́ ìwádìí tó ń ṣe. Wọ́n gbà pé, ó yẹ kí ẹni tó ń lo ìmọ̀ yìí kíyèsí àwùjọ tó ni iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ tó ń ṣe ìtúpalẹ̀ rẹ̀ dáadáa, kí ó kíyèsí ìtàn tó rọ̀ mọ́ ìgbé-ayé àwọn olùṣẹ̀dá irú iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀, kí ó tún kíyèsí afọ̀ lítíréṣọ̀ náà dáadáa láti mọ ìbáṣepọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú àwọn olùgbọ́ tàbí òǹkàwé lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀, kí ó sì ṣàkíyèsí ọ̀nà àgbéjáde iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ náà. Ọ̀kan lára àwọn agbátẹrù ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbépọ̀ ló sọ pé, ó lẹ́tọ̀ọ́ kí gbangba dẹkùn, kí kedere sì bẹ̀ ẹ́ wò nínú iṣẹ́ olùwádìí nípa ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀. Àwùjọ àti lítíréṣọ̀ kò ṣeé yà sọ́tọ̀ síra wọn. Inú àwùjọ ni a ti ń ṣe àtòpọ̀ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí à ń sọ di lítíréṣọ̀. Ẹ̀yí hàn kedere nínú èrò Ògúnṣínà (1988: 85) nígbà tó ń gbìyànjú láti ṣe àpèjúwe lítíréṣọ̀ báyìí:

> ... àfihàn àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́... bí i díígí tó jẹ́ afojú-ẹni-hàn ni lítíréṣọ̀ jẹ́ fún àwùjọ... kì í ṣe pé lítíréṣọ̀ ń fi àwùjọ hàn nìkan, àtúpalẹ̀àwùjọ ló ń ṣe.

Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé kò sí ohun tó wà nínú àwùjọ tí kò lè fara hàn nínú lítíréṣọ̀ àwùjọ kọ̀ọ̀kan, ìwúlò lítíréṣọ̀ yóò

tayọ ọ̀rọ̀ àwàdà tàbí ẹ̀fẹ̀ lásán. Ìyẹn gan-an ni èrò àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo lítíréṣọ̀.Akìwọwọ (1986: 112) sọ pé:

> ... *ẹwù, ìfẹ́* àti *àìní* jẹ́ ohun mẹ́ta pàtàkì tí ó jẹ́ kí àwa ẹ̀dá lè wà ní àjùmọ̀gbé-pọ̀. *Ẹwù* ni ohun tó wu ni, ẹwù náà sì ni ń fà á tí a fi ń ní ìfẹ́ sí ǹǹkan. Ẹwù ni ẹbọ tí a ń fi tán àìní, ìfẹ́, bí àpèjẹ́ rẹ̀ ti rí, ni ohun tí a fẹ́. Nígbà púpọ̀, ohun tí ó wu ni kì í wà ní àrọ́wọ́tó ẹni. A sì lè má fẹ̀ ohun tí ó wu ni...

Ohun tí a rí fàyọ nínú èrò onímọ̀ yìí ni pé, kò sí ohun tó ń fa àjọgbépọ̀ àwa ẹ̀dá ju ọ̀rọ̀ ìfẹ́ tí a ní sí ara wa àti àǹfààní tí à ń jèrè lára ara wa. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú pé, abala mẹ́rin ni àfojúsùn tíọ́rì yìí nínú ìtúpalẹ̀ afọ̀, abala àwùjọ àti afọ̀ ni àwọn onímọ̀ tí a yẹ iṣẹ́ wọn wò kọjá tẹpẹlẹ mọ́ jù lọ nínú àlàyé wọn. Ní ti abala afọ̀ lítíréṣọ̀ pẹ̀lú ìṣẹ̀dá rẹ̀ gan-an tó jẹ àwọn agbátẹrù ìfojú ìmọ̀ ìbágbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ lógún, a lè sọ pé àjọṣepọ̀ tàbí ìkọ́wọ̀ọ́rìn wà láàrín ọ̀nà àgbéjáde lítíréṣọ̀ àti ìṣẹ̀dá rẹ̀ nínú àwùjọ. Lóòótọ́, ojú lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ ni àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí fi wòye ohun tí wọ́n pè ní àgbéjáde afọ̀ (text) àti ètò kárà-kátà lórí irú afọ̀ bẹ́ẹ̀. Lára àwọn tó pilẹ̀ èrò yìí ni Hypolyte Taine (1963), Robert, Escarpit (1968 àti 1971) àti àwọn mìíràn bẹ́ẹ̀. Taine (1963: 417-418) tilẹ̀ sọ pé:

> The literary phenomenon cannot be the work of art itself, but rather, the meeting and sometimes the clashing of two free act, one of the production and the other of their moral

and social relation. There is also another man in literature, a writer for a reader and a reader for a writer.

Iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ kì í ṣe ohun tó dá dúró láàyè ara rẹ̀ bí kò ṣe ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin ǹǹkan méjì, àkọ́kọ́ ni àtiwáyé iṣẹ́-ọnà pẹ̀lú àwọn tí yóò ṣe àmúlò rẹ̀, pẹ̀lú ìhùwàsí àti ìbáṣepọ̀ tó wà láàrin wọn. Ẹlòmíràn tó tún ṣe pàtàkì nínú lítíréṣọ̀ ni; òǹkọ̀wé tó wà fún òǹkàwé àti òǹkàwé tó wà fún òǹkọ̀wé.

Pẹ̀lú àgbéyẹ̀wò èrò àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbépọ̀-wo lítíréṣọ̀ yìí, a lè ṣe ìsọníṣókí èrò wọn báyìí:

i. Ẹ̀so àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́. Àwùjọ àti lítíréṣọ̀ kò ṣe é yà sọ́tọ̀ síra wọn.

ii. Ẹni tí yóò lo ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wò lítíréṣọ̀ ṣe ìtúpalẹ̀ èyíkéyìí nínú afọ̀ lítíréṣọ̀ gbọ́dọ̀ máa ṣe àkíyèsí àwọn ǹǹkan mẹ́rin wọ̀nyí: Iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀, olùṣẹ̀dá lítíréṣọ̀, àwùjọ tó bí lítíréṣọ̀, àti àwọn tí a ṣẹ̀dá rẹ̀ fún.

iii. Lítíréṣọ̀ yàtọ̀ sí ẹ̀ka-ìmọ̀ ìtàn (History) àwùjọ. Fún ìdí èyí, ọ̀nà ẹ̀rọ ni lítíréṣọ̀ fi ń gbé àwùjọ kalẹ̀ dípò ìtàn àwùjọ lọ́nà tààrà. Ìyẹn ni pé ìpàrokò jẹ́ ọ̀kan lára èrò wọn lórí ìtúpalẹ̀ afọ̀ lítíréṣọ̀.

iv. Ohun tó yẹ kó jẹ́ ẹni tó ń lo tíọ́rì yìí fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ lógún ni láti wá ọ̀nà-àbáyọ sí àwọn ìṣòro tó ń kojú àwùjọ nípasẹ̀ kókó-ọ̀rọ̀ tó ń súyọ nínú afọ̀ lítíréṣọ̀.

v. Ó lẹ̀tọ̀ọ́ kí ẹni tó ń ṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ máa kíyèsí ìhun lítíréṣọ̀ pẹ̀lú àṣà àti ìṣe àwùjọ tó ni ín, kí àwọn méjèèjì lè máa ran ara wọn lọ́wọ́.

**Tíọ́rì Ajẹmọ́-Ìṣe-Ọkàn**

Tíọ́rì ajẹmọ́-ìṣe-ọkàn ni a mọ̀ sí psycho-analysis theory. Àfojúsùn àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí ni ìlànà tí àwọn ènìyàn ń gbà ṣe àmúlò ẹ̀yà ara wọn láti gbé òye, ìmọ̀ àti ọgbọ́n yọ nípa ohunkóhun tó bá wà ní àyiká wọn. Lábẹ́ iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀, tíọ́rì yìí tẹpẹlẹ mọ́ àwọn tó ń lo lítíréṣọ̀ ju àwọn tó ń ṣẹ̀dá rẹ̀ lọ. Ìyẹn ni pé, bí àwọn tó ń gbọ́ ìpohùn tàbí àwọn oǹkàwé ti ń ṣe àmúlò ẹ̀yà ara wọn láti fa ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye yọ nínú iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ ló jẹ àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí lógún nínú ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀. Lára àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí ni Piaget, J. (1932), Edward L. Thorndike (1949), J.B. Watson (1958), Fredrick, Skinner (1961) àti Sigmund Frued, (1963). Ọkọ̀ọ̀kan àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ni wọ́n dá àbá lórí bí àwa ẹ̀dá ṣe ń dàgbà láti inú ọlẹ̀ títí di àkókò tí ènìyàn wà láyé láti máa gbé ǹǹkan ṣe.

Ohun tó jẹ àwọn onímọ̀ yìí lógún jù lọ ni àjọṣepọ̀ tó ń wáyé nínú àwọn ẹ̀yà ara ènìyàn, tí ènìyàn fí ń ní àǹfààní láti ṣe àṣeyọrí lórí ohunkóhun tí a bá dáwọ́ lé. Wọ́n gbàgbọ́ pé ọkàn ni olúborí gbogbo àwọn ẹ̀yà ara tí à ń lò láti ṣe ohunkóhun. Ní pàtàkì jù lọ, wọ́n gbàgbọ́ pé:

i. èrò ọkàn ni ènìyàn lè fi túmọ̀ iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀.

ii. ìrònújinlẹ̀ ló lè jẹ́ kí ènìyàn mọ bí ayé ti rí. (*reality principle*)

iii. àwọn ẹ̀yà ara ènìyàn a máa ṣiṣẹ́ bí ọkàn ti ń darí wọn.

iv. ọkàn ló máa ń darí òfin ìfẹ́ àti ìgbádùn (*pleasure principle*)

v. ìrírí inú àwùjọ a máa ran èrò ọkàn lọ́wọ́ láti ṣiṣẹ́ (*heredictory principle*)

vi. olúborí èrò ọkàn ẹ̀dá ni wíwà ní àlááfíà àti ayọ̀.

vii. àjẹbí tàbí àbímọ́ máa ń darí ènìyàn láti hu àwọn ìwà kan.

viii. ìpele ìpele ni ẹ̀dá ń mọ iyì àwùjọ rẹ̀ láti ìpele aròbó (*pre-oedipale stage*), ìpele ọmọdé (*oedipal stage*), ìpele màjèsín (*Adolescence*), Àgùnbánirọ̀ (*young adulthood*), Gẹ́ńdé/Ìgìrìpá[1] (*Middle adulthood*), Àgbà (*later adulthood*), Arúgbó (*old ages).*

## Ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn

Tíọ́rì Ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn ni a mọ̀ sí psycho-Social Theory. Tíọ́rì méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ló parapọ̀ di ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn. Tíọ́rì àkọ́kọ́ ni ìmọ̀-ìbágbépọ̀ tí àwọn agbátẹrù rẹ̀ gbàgbọ́ nínú àjọṣepọ̀ tó ń wáyé láàrin àwa ẹ̀dá àti ipa rẹ̀ lórí ìdàgbàsókè àwùjọ, ìkejì sì ni ìmọ̀ ajẹmọ́-ìṣe-ọkàn. Ohun tí ó mú díẹ̀ lára àwọn onímọ̀ lítíréṣọ̀ gbìdánwò àkànpọ̀ tíọ́rì ajẹmọ́-ìṣe-ọkàn àti ti àwọn onímọ̀ ìbágbépọ̀ ni pé, iṣẹ́ ìwádìí wọn jẹ mọ́ ìṣòro inú àwùjọ tí ẹ̀dá ènìyàn

kọ̀ọ̀kan ṣe okùnfà rẹ̀ látàrí èrò ọkàn wọn. Wọ́n sì gbàgbọ́ pé, ọmọ iná là á rán síná ni ọ̀rọ̀ tíọ́rì ìbágbépọ̀. Fún ìdí èyí, ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ nínú èyí tí a ti rí Bámidélé (2000) àti Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2013) ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí níí ṣe àkànpọ̀ àwọn tíọ́rì méjèèjì yìí fún ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ tí ó nípa pàtàkì lórí ìyanjú-ìṣòro àwùjọ. Èyí ni àwa náà gùn lé láti fi túmọ̀ àwọn kókó-ọ̀rọ̀ ajẹmọ́-aáwọ̀ nínú ewì Adébáyọ̀ Fálétí.

Àwọn agbátẹrù tíọ́rì yìí ní ìgbàgbọ́ nínú àwọn ìrírí ẹ̀dá ènìyàn nínú àwùjọ àti bí ìrírí náà ti ń kó ipa nínú ìrònú, ìṣesí, ìhùwàsí àti gbogbo ìgbòkègbodò wọn nínú ètò ìbágbépọ̀. Wọ́n gbàgbọ́ pé, àwùjọ tí ènìyàn bá dàgbà sí ló máa ń hun ìwà tí ènìyàn yóò máa hù sílẹ̀ fún wọn. Fún ìdí èyí, tí àwọn ènìyàn bá ti ń hu ìwà tó yàtọ̀ síti inú àwùjọ rẹ̀, ó ṣeé ṣe kí ó jẹ́ pé ìrònú tirẹ̀ tayọ ti irúfẹ́ àwùjọ bẹ́ẹ̀. Bákan náà ni wọ́n gbà pé ìforíkorí àti ìfikùnlukùn àwọn ènìyàn lè ràn wọ́n lọ́wọ́ láti lè yanjú ìṣòro inú àwùjọ wọn. Ohun tí ó ṣe pàtàkì jù lọ sí àwọn agbétẹrù tíọ́rì yìí, pàápàá jù lọ, àwọn tí wọ́n ń lò ó fún àyẹ̀wò iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ ni pé ìṣesí àti ìhùwàsí àwọn ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan lọ́tọ̀ọ̀tọ̀ nínú àwùjọ ló máa ń jẹ́ láàríjà iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀. Nítorí náà, lámèétọ́ tó bá ń lo tíọ́rì yìí fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́-ọnà ajọmọ́-lítíréṣọ̀gbọ́dọ̀ máa ṣe àkíyèsí èrò àwùjọ, ìhun àwùjọ, ìhùwasí àwọn ènìyàn àti ojúṣe tí àwùjọ ń fẹ́ lọ́wọ́ wọn nínú àgbékalẹ̀ irúfẹ́ iṣẹ́-ọnà ajẹmọ́-lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀.

Ní ti Bámidélé (2000:89), àwọn ewu tó wà nínú ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ àti okùnfà ewù náà ni tọ́ka sí gẹ́gẹ́ bí àfojúsùn tíọ́rì

yìí. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2013:136) náà gbìyànjú láti wòye ipò tí ìrònú àwa ẹ̀dá ènìyàn ń wà nígbà tí a bá fẹ́ pilẹ̀ ohun ọ̀tun tí a kò tíì dáwọ́ lé rí. Onímọ̀ yìí fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ipa pàtàkì ni ọkàn ń kó nínú ìṣesí àti ìhùwàsí wa nípa àgbéjáde èrò ọ̀tun nínú àwùjọ. Nítorí náà, ipa tí àwa ẹ̀dá ń kó nínú onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ wa níí ṣe pẹ̀lú akitiyan èrò-ọkàn wa. Ẹ̀yí gan-an ni àfojúsùn àwọn agbáterù tíọ́rì yìí. Ní pàtàkì jù lọ, wọ́n gbà pé:

i. Ọkàn ló máa ń darí gbogbo àwọn ẹ̀yà ara ènìyàn yòókù. (*psycho-motor principle*)
ii. Ìrònújinlẹ̀ ló lè jẹ́ kí ènìyàn mọ bí òfin àwùjọ rẹ̀ ti rí (*reality principle*)
iii. Ọkàn ló máa ń jẹ́ kí á mọ ìtumọ̀ ìgbáyégbádùn (*pleasure principle*)
iv. Ìrírí ènìyàn nínú àwùjọ a máa ran èrò-ọkàn lọ́wọ́ láti wo ṣààkun ayé (*heredictory principle*)
v. Àjẹbí tàbí àbímọ́ máa ń darí ènìyàn nínú ètò ìbára-ẹni-gbépọ̀ láti hu àwọn ìwà kan (*heredictory and affectiveprinciple*)
vi. Ìpele ìpele ni ènìyàn ń mọ iyì ètò ìbágbépọ̀ inú àwùjọ rẹ̀ láti ìpele arọ̀bọ́ (*pre-oedipale stage*), ìpele ọmọdé (*oedipalstage*), ìpele màjèsín (*adolescent*), agùnbánirọ̀ (*young adult-hood*), géńdé/ìgìrìpá (*middle adult-hood*), àgbà (*later adult-hood*), àti arúgbó (*old-age*).

vii. Olúborí èrò-ọkàn ẹ̀dá ni wíwà ní àláàfíà àti ipò ayọ̀ (*affective principle*)

Tíọ́rì yìí ni ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn, tí àfojúsùn àwọn agbátẹrù rẹ̀ jẹ mọ́ wíwo ipa tí èrò-ọkàn àwọn ẹ̀dá ènìyàn lápapọ̀ ń kó nínú orísun àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú àwùjọ wọn àti ọ̀nà ti wọ́n lè gbà lo èrò-ọ̀kàn wọn náà láti yanjú ìṣòro ètò-ìbára-ẹni-gbépọ̀ inú àwùjọ wọn. Fún ìdí èyí, ìmọ̀ràn tí Adébáyọ̀ Fálétí máa ń gba àwọn ènìyàn nínú ewì rẹ̀ láti kíyèsí ipò tí ọkàn wọn wà nígbà tí wọ́n bá ń lo àwọn ìpèdè tí ń dá aáwọ̀ sílẹ̀ ni iṣẹ́ yìí dá lé. Bí àjọṣepọ̀ṣe ń wáyé láarin àwọn ènìyàn, tí aáwọ̀ sì ń wáyé láàrin wọ́n, wọ́n níláti máa kíyèsí ipò tí ọkàn wọn wà kí wọ́n tó lo èdè èyíkéyìí. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ọ̀rọ̀ tútù a máa yọ obì lápò, ọ̀rọ̀ burúkú a máa yọọ fà lápó.

Níbi tí aáwọ̀ bá ti wáyé, àwọn ìpèdè kan kì í sáábà wọ́n níbẹ̀. Ó tilẹ̀ ṣeé ṣe kí ó jẹ́ èdè tí ènìyàn bá pè ni yóò ṣe okùnfà aáwọ̀. Lára irú àwọn ìpèdè bẹ́ẹ̀ ni ìpèdè tó jẹ mọ́ èébú, èpè (èdè òdì), ẹ̀fẹ̀, òwe (abàmì), ẹ̀gàn, àbùkù, ìgbéraga, irọ́ pípa, àbòsí ṣíṣe àti èdè agọ̀. Àwọn ìpèdè wọ̀nyí àti irúfẹ́ wọn mìíràn ló ń ṣúyọ nínú àwọn ewì tí Adébáyọ̀ Fálétí ti kọ sínú ìwé eré-onítàn, ìtàn àròsọ àti ìwé ewì lórí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ ìwà ìgbéraga, ìwà àìbìkítà, ìwà ojúkòkòrò, àìnífaradà, ìmọ̀-tara-ẹni-nìkan (Anìkànjọpọ́n), àbòsí ṣíṣe, ilẹ̀ dídà, ọgbọ́n àgbọ́njù, ìlara ọmọnìkejì ẹni àti ìwà jàgídíjàgan. Àfojúsùn Adébáyọ̀ Fálétí lórí irú àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ aáwọ̀ wọ̀nyí àti irúfẹ́ wọn mìíràn ló máa ń ṣe okùnfà àwọn

èdè ajẹmọ́-aáwọ̀ tí a tọpinpin pé ó máa ń ṣúyọ nínú àwọn ewì rẹ̀. Èyí jẹ́ kí á wo bí Adébáyọ̀ Fálétí ti ń lo àwọn ìpèdè tí ó jẹ mọ́ ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn wọ̀nyí nínú àwọn ewì rẹ̀ lọ́kọ̀ọ̀kan báyìí.

## Ìhà tí Àwọn Ènìyàn ń kọ sí Ìpèdè Ajẹmọ́-Èébú

Èébú ni ìlànà tí à ń gbà fi ẹnu tẹ́ńbẹ́lú nǹkan tàbí kí á ṣáátá nǹkankan láti yẹpẹrẹ rẹ̀ tí kò ní í lè jọ àwọn ènìyàn lójú. Àwòrán òdí ni ìpèdè èébú máa ń yà nípa nǹkan. Bí ó bá jẹ́ ènìyàn ni à ń bú, a lè fi àwọn ẹ̀yà ara rẹ̀ tí kò dá pé bú u tàbí kí á wo àléébù tí ó wà nínú àbùdá ìṣẹ̀dá-àdáni rẹ̀ láti láálí ẹni náà tí yóò sì wọ̀ ọ́ ní akínyẹmí ara. Nínú ìwé *Ewì Adébáyọ̀ Fálétí: Apá Kinní*, Ọlátúnjí (1982: 2-5) ṣàfihàn bí Fálétí ti gbé àwọn èdè ajẹmọ́-èébú kalẹ̀ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣelẹ̀ láàrin Oníbodè Lálúpọn àti Àyìndé Onílù Ọba Àyàntọ̀lá. Ó ní:

> Bẹ́ẹ̀ sì ni bá ò bá ní í purọ́
> Tá ò ní gbẹ̀ṣẹ̀ òrìṣà
> Tá ò ní fàbòsí sọgbá àlapà digbáa lúúrú
> Oníbodè Lálúpọn burẹ́wà lọ́kùnrin ọjọ
> Orí rẹ̀ tẹ́ rẹrẹ níwá tẹ́ rẹrẹ lẹ́yìn bí ìlù ìgunnu
> Ó rìpó apá rìpó ẹsẹ̀ bí ìmọ̀dò
> Ètè òké nípọn bí ògiri àbátaá
> Jọ̀jọ̀mèrì ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ̀ sùn léra wọn mọ́lẹ̀ bí ìlẹ̀kẹ̀ ọba
> Ẹnu rẹ̀ wá rí tìpìrì... Ọlátúnjí (1982: 2-5)

Nínú ewì yìí, a rí okùnfà aáwọ̀ bí èké ṣíṣe àti irọ́ pípa láti ṣe àkóbá fún Àyìndé lọ́dọ̀ Oníbodè Lálúpọn. Ìlà àkọ́kọ́ ni a ti rí agbára tí ń bẹ nínú èdè (àyàn) nínú àwùjọ Yorùbá. Àgbà ọ̀rọ̀ tó wà ní ìlà karùn-ún àyọlò yìí gan-an ló fi hàn pé kì í ṣe èdè yẹpẹrẹ ni àyàn gbé kalẹ̀. Irúfẹ́ èdè èébú báyìí ni a

ń pè ní ọ̀rọ̀ burúkú tí í yọ idà nínú apó. Àwọn àfiwé tààrà tó hàn ní ìlà kẹwàá sí ìlà ogún nínú àyọlò òkè yìí ni èdè èébú tó wọ akínyẹmí ara Oníbodè Lálúpọn, tí ó fi gègùn de Àyìndé ní àbọ̀ ìlú Ìbàdàn láti dá sẹ̀ríà fún un. Bí a bá kíyèsí kókó-ọ̀rọ̀ ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn pé, ọkàn ló máa ń darí gbogbo àwọn ẹ̀yà ara ènìyàn yòókù, ìyẹn (psycho-motor principle), ìyà kò bá jẹ Àyìndé bí kì í bá ṣe pé ó tètè ronú jinlẹ̀ láti mọ bí òfin àwùjọ rẹ̀ ti rí, ìyẹn (reality principle). Èyí ló sì mú Àyìndé bọ́ lọ́wọ́ ìyà tí Oníbodè Lálúpọn gbèrò lọ́kàn rẹ̀ láti fi jẹẹ́. Oníbodè Lálúpọn náà sì dárí ji Àyìndé nítorí pé ó mọ ìtumọ̀ "Mo jẹun Èjìgbò, mo jẹun Ìwó. Mò jẹun Oníîbodè Lálúpọn" tí Àyìndé ní lọ́kàn tirẹ̀ gan-an dípò èdè èébú tí àwọn ènìyàn yí èdè àyàn rẹ̀ sí lọ́dọ̀ Oníbodè Lálúpọn.

Nítorí pé Àyìndé ti dàgbà dé ìpele tí yóò ti mọ iyì ètò ìbágbépọ̀ inú àwùjọ rẹ̀ni ó fi lo ọgbọ́n tí ó fi gba ara rẹ̀ kalẹ̀ lọ́wọ́ Oníbodé Lálúpọn, tí Akéwì fi sọ pé:

Ó ní ohun tẹ́ẹ ṣe tó wù mí jù ni mo ń wí pé

> Mo jẹun Èjìgbò, mo jẹun Ìwó
> Mò jẹun Oníîbodè Lálúpọn"
> Bàbá Àgbà ní "Háà
> Má bìínú, aláyàn, ọmọ̀ọ̀ mi
> N ò mọ̀ pé ohun tó rẹwà bẹ́ẹ̀
> Òun lò ń fọmọle í wí... Ọlátúnjí (1982: 4)

Aáwọ̀ ńlá ni yóò bẹ́ sílẹ̀ láarin Àyìndé àti Oníbodè Lálúpọn, bí kì í bá ṣe pé àwọn méjèèjì kó ara wọn ní ìjánu. Bí Àyìndé bá bínú níwájú Oníbodè Lálúpọn nígbà tí ìyẹ̀n gègùn dè é, àwọn méjèèjì kò níí rí ojútùú ọ̀rọ̀ pé kì í ṣe èdè èébú ni

èdè àyàn Àyìndé tí àwọn aláṣìtú-èdè fẹ́ fi ṣe okùnfà aáwọ̀ láàrin wọn.

## Ìwà Ìkà àti Àwọn Ìwà Ibi tí ńṣe Okùnfà Èdè Ajẹmọ́-Èpè

Ọ̀kan lára àwọn ewì-àwíṣẹ Yorùbá tó máa ń sáábà ní èròjà oògùn búburú nínú àkóṣe rẹ̀ ní ìlànà gbàlákọ ni Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2013:14-16) pe èpè. Ìdàkejì èdè ìwúre ni èdè tí à ń lò fún èpè jẹ́. Èdè èpè kì í ṣe èdè gbẹ̀fẹ́ tàbí èdè atura rárá. Bí ó tilẹ̀ wù kí ó kéré tó, èdè èpè nira ju èdè ìwúre lọ. Kò sí ẹ̀dá ènìyàn tí ń fẹ́ kí wọ́n ta àṣẹ èpè lé òun lórí. Àwọn ìṣesí tàbí ìhùwàsí tó ń ṣe okùnfà èdè ajẹmọ́-èpè nínú àwùjọ ènìyàn ni olè jíjà, ilẹ̀ dídà, ìpànìyàn tàbí oríṣìí àwọn ìwà ìkà mìíràn. Àpẹẹrẹ irú èyí ló hàn nínú *Báṣọ̀run Gáà*, nígbà ti inú bí ọba Abíọ́dún Adégoolú lórí ìwà tí Gáà àti àwọn ẹmẹ̀wà rẹ̀ hù nínú ìlú Ọ̀yọ́. Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ẹkún ní í bá ikun wá. Àjọgbépọ̀ Gáà pẹ̀lú àwọn Ọba ìṣáájú nínú ìlú Ọ̀yọ́ tí kò rọgbọló ṣe okùnfà ìpèdè ajẹmọ́-èpè tó wáyé lẹ́nu Ọba Abíọ́dún Adégoolú pé:

*Bẹẹ l'ayà ẹṣìkà*
*Bẹẹ riku Gáà ẹṣòótọ*
Iṣẹ ibi a ma a b'áṣebi lọ
Gbogbo ẹnyin t'ẹ ngbimọọ̀tẹ̀
T'ẹ nda'lu Ọyọ ru
T'ẹẹ fẹ tori owo s'Ọyọ d'ìmẹ́ẹ́rí
T'ẹ ntori t'ara nyin tabuku
Fun gbogbo ilẹ Yoruba
Ẹnyin t'ẹ 'ò jẹk'Ọba o n'idẹrun
lori oye rẹ
T'ẹ 'ò jẹk'Ọba ó f'ẹdọ lori òróoro

Lori ọba
B'ẹẹ bu 'kele lọwọ, ẹ 'ò ni r'ọbẹ fi run...
Fálétí (1976:140-141)

Kò sí ẹ̀dá ènìyàn tí a lè dajú irú ìpèdè yìí kọ láìṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ tó ká ènìyàn lára tó èyí tí Gáà ṣe fún àwọn ará Ọ̀yọ́ nínú ìwé *Baṣọ̀run Gáà* tí a ti fa àyọlò ewì Fálétí yìí yọ. Tí a bá wo àwọn èdè òdì tó wà nínú àyọlò òkè yìí, a óò rí i pé èdè ajẹmọ́-èpè ló burú jù lọ lásìkò tí aáwọ̀ bá ṣẹlẹ̀ nínú àwùjọ. Fún ìdí èyí, ó yẹ kí ènìyàn máa kíyèsí ìwà tí yóò máa hù àti èrò rẹ̀ sí àwọn ènìyàn inú àwùjọ rẹ̀, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, irúfẹ́ àwọn ìpèdè ajẹmọ́-aáwọ̀ yìí ni yóò máa wáyé láwùjọ wọn. Ẹ tún wo bí Adégoólú ti fi Gáà ré nínú *Báṣọ̀run Gáà* nígbà tí ọwọ́ ìlú tẹ̀ ẹ́ lórí gbogbo ìwà ìkà tí ó ti hù. Ó ní:

Gáà, ìlú Ọ̀yọ́ rẹhin rẹ
Aganjú rẹ́hin rẹ
Ọ̀ránÿàn rẹ́hìn rẹ    Fálétí (1972:136)

Kí Yorùbá tó máa ṣẹ́ èpè Alájọbí tàbí ti Alálẹ̀ lé ènìyàn lórí, ó dájú pé ẹni náà ti hùwà èpè. Ewì tí Fálétí kọ sínú *Nwọ́n Rò Pé Wèrè Ni* tọ́ka sí ilẹ̀ dídà láàrin Bàbá Rámọ́ àti Àrẹ̀mú ọ̀rẹ́ rẹ̀, tí ó ṣe okùnfà èpè tí adájọ́ yán fẹ́ẹ́rẹ́ nínú ọ̀rọ̀ rẹ̀ pé:

Ṣùgbọ́n, èèwọ̀ ni ẹnìkan kò gbọdọ̀ dale ọ̀rẹ́
Iwọ dalẹ̀ ni tirẹ, ilẹ̀ sì dà ọ́ nù.
Fálétí (1972:136)

A óò rí i pé ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn Ìbọ láwùjọ Yorùbá kì í ṣe ohun tí a kàn lè máa fi ènìyàn ré lórí rẹ̀ láìjẹ́ pé ó hu irú ìwà tí Fálétí gbé wọ Bàbá Rámọ́ nínú eré náà.

## Ìpèdè Ajẹmọ́-Ẹ̀gàn

Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ẹ̀gàn kì í pé kóyin má dùn. Bí èyí bá rí bẹ́ẹ̀, á jẹ́ pé wẹ́kú ni èrò àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn ṣe pẹ̀lú oríṣìí àwọn èdè ajẹmọ́-ìpẹ̀tù-sí-aáwọ̀ tó ṣúyọ nípa ọ̀rọ̀ pípẹ̀gàn ènìyàn nínú ewì Adébáyọ̀ Fálétí lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan. Nínú ewì "Ẹ̀dá Kò Láròpin", Akéwì fi hàn wí pé àròkàn ní í fa ẹkún àsun-ùn-dákẹ́. Bí a bá ń pẹ̀gàn ènìyàn, ká máa rántí àyànmọ́ ẹ̀dá tí kò lè tàsé. Ó ní:

> Ẹ wo iṣẹ́ Èdùmàrè
> Bí ó ti jẹ́ kàyéfì ńlá tó!
> Ó fìbùkún fáwọn aláìníṣẹ́ lápá
> Ó gbọ́lá *fọ́mọ òkú ọ̀lẹ!*
>
> Ọlátúnjí (1982:21)

Kì í ṣe gbogbo ènìyàn tí kò níṣẹ́ lápá tàbí tí wọ́n jẹ́ òpìjẹ̀ ni ọ̀lẹ̀. Ó lè jẹ́ pé àyànmọ́ wọn ló gbà bẹ́ẹ̀. Àwọn aláìníṣẹ́ lápá tí wọ́n ti ń pẹ̀gàn wọn ṣáájú gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú ìlà kẹrin àyọlò òkè yìí "Ó gbọ́lá *fọ́mọ òkú ọ̀lẹ*!", ni akéwì tọ́ka sí pé Ọlọ́run yí ìgbà padà sí rere fún wọn kúrò ní ipò *"ọmọ òkú ọ̀lẹ"* tí wọ́n ti ń pè wọ́n tẹ́lẹ̀. Akéwì ní "Ó fìbùkún fáwọn aláìníṣẹ́ lápá" láti jẹ́ kí á mọ̀ pé ẹ̀dá kò láròpin. Bí a bá pe irúfẹ́ èdè *"ọmọ òkú ọ̀lẹ"* yìí sí ènìyàn nítorí pé kò níṣẹ́ lápá, aáwọ̀ ńlá lè ṣẹlẹ̀ láàrin ẹni tí ó pe èdè náà àti ẹni tí ó pè é sí. Ìdí nìyí tí akéwì fi gbà pé ìpèdè irú èyí kò tọ̀nà láàrin àwùjọ ènìyàn. Ọ̀nà-èrọ ni Fálétí máa ń gbà fi èdè ewì tirẹ̀ kìlọ̀ ìwà ìbàjẹ́ inú àwùjọ láti dẹ́kun aáwọ̀. Àwọn Yorùbá bọ̀, wọ́n ní, ẹ̀sọ̀ pẹ̀lẹ́ ni ejò ń gun àgbọn. Àwọn náà ni wọ́n tún sọ pé, ẹ̀sọ̀ pẹ̀lẹ́ ni a fi ń pa amúkùru pẹ̀lẹ́.

Lára àwọn ìwà tí ń dá aáwọ̀ sílẹ̀ ni ṣíṣe àbòsí tàbí kí á máa pẹ̀gàn ènìyàn láìdáa lẹ́yìn rẹ̀. Ìwà ìbanilórúkọjẹ́ ni ìwà yìí jẹ́. Àwọn kan a máa pe ara wọn ní A-wí-konko-lójú-ọlọ́rọ̀. Ìtumọ̀ méjì ni èyí ní lábẹ́ ìwà àbòsí ṣíṣe. Lọ́nà àkọ́kọ́, ó já sí ìwà taa-ni-yóò-mú-mi? Lọ́nà kejì, ó já sí ìwà àìfàgbà-fẹ́nìkan tí kì í jẹ́ káyé ó rójú. Nítorí náà, bí àwọn ìpèdè tó jẹ mọ́ àbòsí yìí bá pọ̀ nínú àwùjọ, aáwọ̀ ni yóò tú àwùjọ bẹ́ẹ̀ ká.

Àbùdá-àdáni gbogbo àwa ẹ̀dá ènìyàn ni ìrònú jẹ́. Ẹ̀dá tí kò bá ní ìrònú àròjinlẹ̀, irú wọn ní í bóko Aláwo lọ. Gbogbo ìgbà kọ́ ni ọkàn ènìyàn ń gbọgbẹ́. Bákan náà sì ni pé, ènìyàn kò lè ṣe kí ó má wà ní ipò yìí ní àwọn àkókò kan. Tibi tire yìí ló máa ń ṣe okùnfá ipò tí ọkàn ènìyàn lè wà, tí a sì gbọdọ̀ kíyèsí i, kí á máà ba ṣẹ ẹni náà. Ìyẹn ni àwọn àgbà fi máa ń sọ pé, mọ̀wà fóníwà níí jẹ́ ọ̀rẹ́jọ̀rẹ́.

## Ìpèdè Ajẹmọ́-Àbùkù

Ìtumọ̀ àbùkù ni wíwo abala ibi tí àléébù wà nínú ìṣesí àti ìhùwàsí ènìyàn, kí á wá tẹpẹlẹ mọ́ ọn nínú àríwísí wa nípa rẹ̀ ju àpọ́nlé ìwà rere tí ó hù lọ. Ẹni tí a bá tàbùkù rẹ̀ tàbí tí a kàn lábùkù, kò lè fi ojú rere woni. Ohun tí ó tọ́ ni pé, ó yẹ kí á ṣọ́ra fún àwọn ìpèdè tí ó jẹ mọ́ kíkanni ní àbùkù. Adébáyọ̀ Fálétí náà ní irú èròǹgba wa yìí nínú àwọn ewì rẹ̀ láti fi hàn pé àkíyèsí tó lọ̀ọ̀rìn tí a bá ṣe nípa ìṣesí-ọkàn ni a lè fi yanjú aáwọ̀ nínú àwùjọ, ní ìbámu pẹ̀lú èrò àwọn agbátẹrù ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn. Ẹ wo àpẹẹrẹ àyọlò yìí:

> Ìyá ìyàwó kàndí, kò mọhun tó lè ṣe;
> Ó pẹ̀yìn dà, ó lọ sọ fáwọn tẹ̀ẹ̀kùlé

Lòun Làálà bá kora pẹ̀kí ní gbangba
Ó ní "Jọ̀wọ́, ọ̀rẹ́ ọkọ ìyàwó,
O ò wá wohun tọ́rẹ̀ẹ́ rẹ ń ṣe:
Èlùbọ́ tá à bá rò lámàlà
Lọkọ ìyàwó ti fẹ́rẹ̀ jẹ tán níyàrá"

Ọlátúnjí (1982:30)

Nínú àyọlò òkè yìí, akéwì fi hàn pé, ọgbọ́n inú tayọọjọ́ orí. Ìyá ìyàwó Dòkun kò kó ara rẹ̀ ní ìjánu lórí èdè tí ó fi júwe àna rẹ̀, nítorí pé kò farabalẹ̀ wo ṣàákun ohun tó fa sábàbí ìṣẹ̀lẹ̀ tó ṣẹlẹ̀ sí Dòkun.Aáwọ̀ ńlá ni ìyá ìyàwó Dòkun fẹ́ẹ̀ dá sílẹ̀ pẹ̀lú èdè ẹ̀gàn tó fi júwe ọkọ ọmọ rẹ̀ yìí, bí kì í bá ṣe pé ó pàdé Làálà lójú ọ̀nà, tí ìyẹn sì tètè yí ọ̀rọ̀ náà mọ́ ọn lọ́wọ́ láti dẹ́kun aáwọ̀ yìí. Akéwì fi hàn pé, irú àwọn ìpèdè bẹ́ẹ̀ jẹ́ àbùkù gbáà fún ènìyàn.

## Ìpedè Ajẹmọ́-Ìgbéraga

Ìwà mo-tó-mo-tó àti àìbìkítà-fẹ́nìkan ni àwọn Yorùbá ń pè ní ìgbéraga. Alágbára-má-mèrò sì ni baba ọ̀lẹ. Nítorí pé, ìgbéraga ní í ṣáájú ìparun. Adébáyọ̀ Fálétí gbà pé bí ènìyàn bá ti ń rò nínú ọkàn rẹ̀ wí pé, kò tún sí ènìyàn tó dára ju òun lọ, ẹni náà a máa dá aáwọ̀ sílẹ̀ nínú àwùjọ rẹ̀. Kedere ni èyí hàn nínú ewì kan tí ó pe àkọ́lé rẹ̀ ní "Alágbára-Ilé Àti Alágbára-Oko". Ó ní:

Bọ́mọdé kò bá dóko ẹlòmíì rí,
A máa lérí, a máa fọ́nnu,
Pé kò sẹ́ni tó lè ṣàgbẹ̀,
Tí yóò dóko ju bàbá òun lọ;

Ọlátúnjí (1982:45)

Láti fi hàn pé irú ìpèdè yìí lè dá aáwọ̀ sílẹ̀ láwùjọ, Adébáyọ̀ Fálétí wòye ọ̀nà tí ó lè fi dẹ́kun irúfẹ́ ìpèdè bẹ́ẹ̀, ni ó fi sọ ìtàn àwọn akọni méjèèjì tó hàn nínú ewì náà, kí àtúnbọ̀tán èdè ìgbéraga Alágbára-Ilé lè jẹ́ ẹ̀kọ́ fún àwọn ènìyàn inú àwùjọ rẹ̀. Èyí á sì mú kí aáwọ̀ dínkù nínú àwùjọ

## Ìpèdè Ajọmọ́-Irọ́pípa

Irọ́ pípa ni ìwà àwọn aláìlóòótọ́ ẹ̀dá. Bí ènìyàn bá kúndùn irọ́ pípa, aáwọ̀ ni wọ́n máa ń fi dá sílẹ̀ láàrin àwùjọ wọn. Lóòótọ́ ni pé, àwọn ènìyàn tí wọ́n kọ òtítọ́ pọ̀ ju àwọn tó fẹ́ràn òtítọ́ lọ, síbẹ̀, Fálétí gbàgbọ́ pé ìṣesí àti àwọn ìhùwàsí kan ló máa ń fa irọ́ pípa fún àwọn ènìyàn. Adíjàálẹ̀ ni àwọn òpùrọ́. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni wọ́n sì máa ń mú inú bí àwọn ènìyàn, tí yóò sì di yánpọnyánrin. Èyí ló mú Fálétí sọ pé:

> Níṣojú òpùrọ́ la fi gbọ́ndò, la pèkúté
> Níṣojú oníró la fi papa tá a rẹ́ja pa
> Ṣojú òpùrọ́ lòyìnbó fi bínú wọlẹ̀ lẸ́yìngẹ̀tì
> Ọ̀rọ̀ gbogbo ní í ṣojú òpùrọ́
> Ìwọ ṣá má bàá wọn jiyàn kó má gbòdi lọ nínú wọn
> Purọ́purọ́ aboyinlẹ́nu
> Ìrínisí là á mọ̀wà ènìyàn    Ọlátúnjí (1982:53)

Ìlà karùn-ún àyọlò òkè yìí ni Akéwì ti fi hàn pé, àwòdẹ́kun là á wo àwọn òpùrọ́, kí á tó lè dẹ́kun aáwọ̀ tí irọ́ wọn máa ń dá sílẹ̀ láwùjọ.

**Àgbálọgbábọ̀**

Ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé dandan ni aáwọ̀ láàrin àwùjọ ènìyàn. Àwọn ohun tí ń ṣe okùnfà aáwọ̀ nìkan ni a ní láti kó ara wa ní ìjánu lórí wọn kí aáwọ̀ tó di ogun tàbí ìjà. Ìwádìí yìí sọ ọ́ di mímọ̀ pé ipò tí èrò-ọkàn ènìyàn bá wà lásìkò ìṣẹ̀lẹ̀ èyíkéyìí máa ń ní ipa lórí ìhà tí a ó kọ sí ìṣẹ̀lẹ̀ náà. Fún ìdí èyí, a gbọ́dọ̀ máa kíyèsí èrò-ọkàn wa lóòrèkóòrè kí á tó hu ìwà tàbí kí á tó sọ̀rọ̀. Ìwádìí yìí fi yé wa pé inú ọkàn ènìyàn ni 'ọ̀rọ̀', 'afọ̀', 'èdè', 'ìhónú', 'ìdùnnú', 'ìbànújẹ́', àti oríṣìí àwọn ìṣesí àti ìhùwàsí mìíràn pabùdó sí. Ọkàn yìí ní ń gbé ọ̀rọ̀ (tútù) tíí yọbì lápò àti ọ̀rọ̀ (burúkú) tíí yọdà lápó jáde. Ìwádìí yìí tẹ̀lé ìlànà ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn. Àgbéjáde rẹ̀ sì ni pé, kí ìbáṣepọ̀ tó lóòrìn tó wáyé nínú ètò ìbágbépọ̀ àwùjọ, ìrẹ́pọ̀ gbọ́dọ̀ wà nínú ètò ìbágbépọ̀ àwọn ènìyàn.

Ìwádìí yìí tọ́ka sí ìlànà tí Adébáyọ̀ Fálétí ń gbà kìlọ̀ fún wa láti dẹ́kun lílo àwọn èdè tí ó jẹ mọ́ aáwọ̀ nínú àwùjọ wa nínú àwọn ewì rẹ̀. Lóòótọ́ ni pé, kò lè ṣe kí ìjà má wà. Nítorí pé, arẹ́májà kò sí, ajàmáparí ni kò sunwọ̀n. Síbẹ̀ náà, a ní láti dẹ́kun àwọn èdè tó ń dá aáwọ̀ sílẹ̀ nínú àwùjọ. Ìdí ni pé, ọ̀rọ̀ (tútù) a máa yọ obì nínú àpò, tí ọ̀rọ̀ (burúkú) a sì máa yọ idà nínú apó. Èébú, èpè, àpará akọ, ẹ̀fẹ̀, òwe (abàmì), èdè ẹ̀gàn, èdè àbùkù, èdè ìgbéraga àti àwọn èdè tí ó jẹ mọ́ irọ́ pípa ni orírun aáwọ̀ láàrin àwùjọ gẹ́gẹ́ bí ìwádìí yìí ti fi hàn.

Bákan náà ni ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé, ojúṣe àwọn onímọ̀ ìfojú-ìmọ̀-ìbágbépọ̀-wo-ìṣe-ọkàn ni láti máa kíyèsí

ìṣesí àti ìhùwàsí àwọn ènìyàn lórí àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tó jẹ mọ́ aáwọ̀ láti là wọ́n lọ́yè lórí ipò tí wọn yóò máa to tọkàn-tara wọn sí ní àyíká kọ̀ọ̀kan. Èyí ni yóò dẹ́kun ìkọlura, ìbínú, ìfẹ̀hónùhàn, ìtàpórógan, jàgídíjàgan, ọ̀tẹ̀, ogun àti oríṣìí àwọn ìwà mìíràn tí wọ́n jẹ́ àtúbọ̀tán fún aáwọ̀.

## Ìwé Ìtọ́kasí

Abímbọ́lá, W. (1977). *Àwọn Ojú Odù Mẹ́rẹ̀ẹ̀rìndínlógún* Ìbàdàn. O.U.P.

Adéyẹmọ, T.O. (2011). "Ipa Lítíréṣọ̀ AlohùnYorùbá nínú Ètò-Ìṣèlú", nínú *Ẹ̀gin: Jọ́nà Akadá ní Èdè Yorùbá.* Ondó, Department of Yorùbá, School of Languages, Adéyẹmí College of Education, Ondó. No. 2, Vol. 1, o.i 209-214.

Ajíbádé, G.O. (2009). *Finding Female Voice: A Socio-Cultural appraisal of yorùbá Nuptial Poetry*. Germany RUDIGER KOPPEVERLAG.

Akìwọwọ, A. (1986). "Àṣùwàdà Ènìyàn", nínú *Olókun: Ìwé Àtìgbàdégbà ní Àtàtà Yorùbá*, No. 14, January, o.i. 112-123.

Bámidélé, L.O. (2000). *Literature and Sociology.* Ìbàdàn, Stirling Horden Nig. Ltd.

Edward, L. Thorndike (1949). *Educational Psychology*. New York: Monarch Press. Inc.

Fálétí, A. (1968). *Baṣọ̀run Gáà.* Ìbàdàn, Oxford University Press.

Fálétí, A. (1972). *Ìdàámú Páàdì Mínkáílù.* Ìbàdàn, Oníbọn-Òjé Press and Books Industries (Nig.) Ltd.

Fálétí, A. (1976). *Nwọn Ro Pe Wèrè Ni.* Ìbàdàn, Oníbọn-Òjé Press and Books Industries (Nig.) Ltd.

Fánilọ́lá, K.A. (1986). "Gbàǹjo!!! Tíọ́rì fún Lítíréṣọ̀ Yorùbá" Nínú *YORÙBÁ: Journal of Yorùbá Studies Association of Nigeria*. Special Edition o.i 30-47.

Fredrick, Skinner (1961). *Theories of Knowledge*. New York: APPLETON Century-Craft.

Howell, S. (2018). "Hate Speech in Formal Discourse", nínú *MAN*; *The Journal of the Royal Anthropological Institutes.* London, The J.H.U. Press.

Hypolyte, A. Taine (1963). *The French Revolution in Books.* United State, Liberty Fund Inc.

Ibrahim, W.A. (2018). "Àgbéyẹ̀wò Ètò-Ìṣèlú Àti Ìbágbepọ̀ Nínú Àwọn Àṣàyàn Fíìmú Túndé Kèlání" Ph.D Proposal, submitted to Department of Nigerian & Foreign Languages, Olabisi Onabanjo University, Ago-Iwoye.

Luis-Gates, H. (2014). (ed.) *Conflict Theory and Black Literature.* New York, Methem.

Ògúnṣínà, B. (1987). "The Sociology of the Yorùbá Novel: A Study of Isaac Thomas, D.O. Fágúnwà and Ọládẹ̀jọ Òkédìjí" PhD Thesis, Ìbàdàn. University of Ìbàdàn.

Ògúnṣínà, B. (1988). "Women in Yorùbá Ìjálá: A Sociological Perspectives", Bébà tí a kà ní ibi Àpérò Ẹlẹ́ẹ̀kọkàndínlógún. West African Linguistics Society Congress Lagos.

Ọlátúnjí, Ọ. (1982). *Ewì Adébáyọ̀ Fálétí, Ìwé kìn-ín-ní*. Heineman Edu. Books.

Ọlátúnjí, Ọ. (1982). *Adébáyọ̀ Fálétí:A Study of His Poems.* Heineman Edu. Books.

Ọlátúnjí, Ọ. (1984). *Features of Yorùbá Oral Literatures*. Ìbàdàn U.P.L

Ọ̀pẹ́féyìtímì, J.A (2013). "The Articulation of Knowledge, Insight and Wisdom in English and Yorùbá Poems" Winneba, Ghana: nínú Journal of African Cultures and Languages. Vol 02, issue 01, January o.i. 132-141.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí, J.A. (2009). *Women in Yorùbá Culture (A Dozens of Academic Articles).*Ìbàdàn, Penthouse Publications.

Ọ̀pẹ́féyìtímì, J.A. (2014). *Ìtúpalẹ̀ Èpè.* Ilé-Ifẹ̀.: O. A.U Press

Ọ̀pẹ̀fèyítìmí, J.A. (2014). *Tíọ́rì àti Ìṣọwọ́ló-Èdè*. Ilé-Ifẹ̀.: O. A.U Press.

Piaget, Jean (1932). *The Moral Jugdement of the Child*. New York: Harcourt Brace Collier Book Edition.

Roberts, Escarpits (1968). *The Revolution in Books.* UNESCO. Courrier Publications.

Schwariz, J. (1965). *The Magic of Thinking Big.* New York, R.O.P, Inc.

Sigmund, Freud (1963). *An Outline of Psycho-Analysis*. New York: Norton.

Tábí-Àgòrò, A.M. (2017). "Aáwọ̀ àti Ìpẹ̀tùsááwọ̀ Orogún ṣíṣe nínú Àṣàyàn Àlọ́ Onítàn", Pépá tí a kà níbi Àpérò

Ẹgbẹ́-Onímọ̀ Ìjìnẹ̀ Èdè Yorùbá. Ìbàdàn, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Watson, J. B. (1958). *Molecular Structure of Nucleic Acid*. London Nature Publications.